# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose ogbon: Osu keje Ojo kerinlelogun, 2016**

**Akori Oro: Ni itara fun ise Oluwa**

**Eko kika: Galatia 4: 11-18**

## Afihan

Onitara enia je awon okunrin ati obinrin ti won ni iwa igbona-okan, ti won si fi ara won fun idi- pataki kan,awon ise kan tabi ohun ti won gbagbo. Awon abala enia yi je awon ti won ni awon iwa ti o ma nru emi okan won soke lati sise laisi idaduro.

Opolopo enia ninu aiye loni ni won ni itara sugbon ki se fun ohun rere. Awon miran ni itara fun awon ohun-omoluwabi, ti o si le ba ofin mu sugbon ti ko se itewogba ni iwaju Oluwa.

Lowolowo, egbaa-gbeje enia ni o ni itara ninu aiye fun awon idi wonyi:

- Ise oojo won tabi ise ti won yan laayo.
- Eto awon eranko.
- Ago-ara won ti nse erupe.
- Irisi won niwaju awon enia.
- Awon ohun ti Olorun da si ayika wa.

Gbogbo awon itara wonyi je ti ohun asan aiye, eyiti ko le mu enia wo inu Ile-ologo. Lati isinsinyi lo, itara fun ise Oluwa ni o gbodo joba ninu aiye re, ki gbogbo laala re ninu aiye yi maba jasi asan.

## Itara gbodo je koko ninu aiye wa

Ohun ti o gbodo se pataki-julo fun okankokan ninu aiye ni ki won ni itara fun ise baba won ti nbe ni orun, toripe idi-pataki ti Olorun fi da awa eda-enia ni lati ma se ise Re. Bibeli jeri si wipe Olorun fi baba-nla wa Adamu sinu ogba Edeni lati ma ro o ati lati ma so o **Genesisi 2: 15**. Niwon igbati a da awa eda-enia lati ma se ise Olorun, o ye ki a ni itara fun ise-Oluwa; toripe ohunkohun ti o ba leto lati se, o ye ki enia se daradara.

**<u>Itara Ile Re ti je mi tan:</u>** Ki Jesu Kristi to wasi aiye nipa eda-enia, ni ati so asotele nipa Re wipe " itara ile Re ti je mi tan, ati egan awon ti ngan o, subu lu mi" **<u>Orin Dafidi 69: 9</u>**. Jeki ina-itara fun ise Oluwa ma jo kikan ninu aiye re, besini ki o farada egan awon alaigbagbo ti won nta-abuku ba Olorun ati ise Re.

**<u>Jesu se afomo Tempili:</u>** A mu asotele nipa Jesu Kristi se ni Tempili ni nbe ni Jerusalemu, ni igbati o ri awon ti nta malu, aguntan ati adaba pelu awon onipasiparo owo; ti nta ti won si nra ninu Tempili. Jesu fi okun tere se pasan, o si le gbogbo won jade kuro ninu Tempili, o wipe "e mase so ile Baba mi di ile oja tita". Lehina ni awon omo-ehin Re ranti asotele ti a ti so nipa Jesu **<u>Johannu 2: 13-17</u>**. Bere lati oni lo, ma lo si ile-Oluwa ki se fun tita tabi rira, bikose lati sin Olorun ki o si gbiyanju lati ma tun ayika ile-Oluwa se ki o le wa ni mimo; mase woju enia tabi duro de awon alagbase ki o to ma tun Ile-Oluwa ati ayika re se.

**<u>Kristi se abojuto ise Baba Re:</u>** Okan lara awon ohun ti o wumi-ju lara awon iwa Kristi, ti o si je ohun ayin-logo ni wipe, O je asiwaju ti nfi ipinle rere le'le fun awon omo-ehin lati tele. Jesu fi itara fun ise Baba Re han nigbati o nbe ni omo odun mejila. Jesu duro lehin ni igbati won lo si Jerusalemu fun ajo-irekoja, O wa ninu Tempili; O joko larin awon olukoni, O ngbo ti won, O si nbi won leere oro. Nigbati awon obi Re ri, won wi fun wipe awon ti nwa kiri, sugbon Jesu da won lohun wipe "ese ti enyin fi nwa mi kiri, anyin ko mo pe, emi ko le saima wa nibi ise Baba mi?" **<u>Luku 2: 41-49</u>**. Kristiani, e beresini bojuto ise Baba yin ti nbe ni orun, ki e si ni itara fun idagbasoke ise na.

**<u>Ni itara fun ise Baba re ti nbe ni orun:</u>** Awa ti a ti gbala gbodo ni itara, ki a si se gbogbo ohun ti o ye lati wa awon aguntan ile-Israeli ti o sonu lati fa won pada wa sinu agbo gegebi ase Jesu Kristi Oluwa wa. Jesu wipe ki a to awon aguntan ile Israeli ti o nu lo, lati ro won ki won ronupiwada ki won si se ilaja pelu Olorun **<u>Matteu 10: 6.</u>** A ko gbodo da awon ota wa tabi awon alaigbagbo lejo, sugbon a ni lati ni itara fun iyipada won; ki won le kuro ni awon ona buburu won. Nitori bibeli wipe" ayo yio wa ni orun lori elese kan ti o ronupiwada, ju lori olooto mokandinlogorun lo, ti ko se aini ironupiwada" **<u>Luku 15: 7</u>**. Nitorina, e jeki itara yin pa yin run, nitori ti awon ota yin ti gbagbe oro Olorun **<u>Orin Dafidi 119: 139</u>**. Inu le ma bi yin nitori awon ota yin ti ko ka oro Olorun si, sugbon e se iwon ti e le se lati mu won pada si ona ododo.

**<u>Hu iwa gegebi Kristiani:</u>** Ibikibi ti o le wa ninu aiye, ohunkohun ti o le ma se ni igbakugba, e jeki a se awon ise wa bi olufokansin. A ni lati fi iyonu feran ara wa

denudenu gegebi arakunrin ninu Oluwa, ki a si ma b'owo fun ara wa; nipa fifi enikeji wa saju. Niti ise sise, e ma se ole;e ma ni igbona-okan; e ma sin Oluwa **Romu 12: 10-11.** Awon enia ni lati mo iyato larin awa olufokansin ati awon alaigbagbo. Nitorina, e mase jafara ninu itara, e ji giri ninu emi; ki e si ma sin Oluwa pelu gbogbo ipa yin.

**Ni itara fun awon ohun ti o dara ni gbogbo igba:** Lotito ni bibeli wipe ki a ni itara, sugbon itara fun ise Oluwa ati awon ohun rere nikan ni bibeli ntoka si. Tori idi eyi, ipokipoti o le ba ara re, ni itara ni gbogbo igba fun awon ohun rere **Galatia 4: 18**. Ibikibi ti o le wa, o dara lati ni itara, niwon igbati o ba ti je fun ise-rere ni; yala awon alufa tabi awon asiwaju yin wa ni ayika tabi won kosi ni ayika.

## Awon iwa ti a gbodo ni pelu itara

Orun ni ipin re, bi o ba fi awon iwa rere yi kun itara re:

**Fi igbagbo kun itara re:** Sa gbogbo ipa re lati muki igbagbo re tunbo gbile si nipa fifi iwarere ati itara kun igbagbo re. Bibeli wipe ki a fi iwarere kun igbagbo, ati imo kun iwarere. Ati airekoja kun imo; ati suru kun airekoja; ati iwa-bi-Olorun kun suru. Ati ife omonikeji kun iwa-bi-Olorun; ati ifeni kun ife omonikeji. Nitori bi enia ba ni nkan wonyi ti nwon ba si po, nwon ki yio jeki e se ole tabi alaileso ninu imo Oluwa wa Jesu Kristi **2 Peteru 1: 5-8:** Lati inu alaye ti a se, e o ri wipe a nilo lati fi awon iwarere kun itara wa, ki o ba le se itewigba niwaju Oluwa.

**Da iyin po mo itara re:** Kun fun iyin Oluwa , ki o si ni itara fun ise Re; Nigbana ni Oluwa yio jade bi okunrin alagbara, yio ru owu soke bi ologun: yio kigbe, nitoto, yio ke ramuramu; yio si bori awon ota re **Isaiah 42: 10-13**. Niwon igbati a ti mo asiri yi, ni igbakugba ti o ba fe ru owu tabi itara Oluwa soke; fi iyin kun itara re.

**So iberu Olorun po pelu itara re:** Mase jeki aiya re se ilara si awon elese ti won k'oro-jo nipa iwa buburu won, sugbon ni itara ni gbogbo igba pelu iberu Oluwa **Iwe Owe 23: 17**. Ohun ti o yeki o se pataki ni okan re, ni bi iwo yio ti fi iberu Oluwa kun itara re.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Kokanlelogbon: Osu Keje, Ojo Kokanlelogbon, 2016**

**Akori oro: Ni itara fun ise Oluwa** – Apa keji

**Eko kika: Galatia 4: 11-18**

Ao tesiwaju ninu eko wa pelu awon ohun ti a le se ti a ko fini lo itara wa fun Esu.

**Itara re ni lati je nipa imo Olorun**

Ara mi ninu Oluwa, e ni itara fun Olorun, Ki itara na si da-lori imo otito Oluwa. E jeki itara yin fun ise rere wa ni ibamu pelu imo Jesu Kristi, bibeko itara na ko se itewogba si Oluwa **Romu 10: 2**. Kiyesara, ki o si ri daju pe itara re da-lori imo Olorun, nitoripe Satani le ja-gba lati lo fun ere tikalarare.

**Awon iwa ti o lodi si itara fun ise Oluwa**

Opolopo ni awon iwa ti o lodi si itara fun ise Oluwa, sugbon ao menuba ninu won, ninu eko yi.
**Agabagebe:** Ni akoko Oba Dafidi, iyan kan mu fun odun meta. Ni igbati o bere lowo Oluwa, Oluwa si wipe, nitoriti Saulu ni ati nitori ile re ti o kun fun eje; nitoripe o pa awon ara Gibeoni ti awon omo Israeli ti bura fun lati dabobo won ni igba-aiye Josua. Saulu se eyi ni itara re fun awon omo Israeli ati Juda **2 Samueli 21: 1-2**. Mase huwa bi oba Saulu ti o fi agabagebe kun itara re, nipa lilo itara re lati te awon enia lorun ti kosi fi te Olorun lorun. Iru iwa bayi je asilo-itara ti o si le fi aye gba Satani lati gbile ninu aiye enia.

**Eko eke:** Opolopo olukoni eke ni o wa ninu aiye loni; awon ti won nyi oro Oluwa pada lati mu ife inu won se. Iru awon olukoni eke wonyi wa lopolopo kakiri agbaye, won nsi awon ese-bibeli tumo, nitori ere iwa imotara-eni-nikan won. Paulu aposteli kilo nipa awon olukoni-eke wonyi fun awon ara Galatia, wipe "nwon nfi itara wa nyin, sugbon ki se fun rere; nwon nfe ja nyin kuro, ki enyin ki o le ma wa won" **Galatia 4: 17**. Fetisile, itara enikeni ti o ba nyi oro Oluwa pada ki se ojulowo, besini iru itara be ki se fun Oluwa sugbon o l'odi si Oluwa. Nitorina, kiyesara fun awon olukoni tabi alufa ti won nwa ona lati ri ojurere re, nitori ipinu okan opolopo won ko dara. Ohun ti won nfe ni lati ya o kuro ninu otito Ihin-rere, ki o ba le ri aye fun won, tabi ki o le je-eje ohun nla tabi ki o le darapo mo ohun ti won gbagbo. Itara re ni lati je nipa otito oro

Olorun ki o to le se itewogba niwaju awon orun.

**<u>Aigboran ati irira:</u>** Gbogbo itara ti o ba se aigboran si Oluwa tabi ti o huwa lodi si oro Olorun, won je itara ti Satani. Nitorina, fi iwa igboran kun itara re, yago fun ese ati awon ohun irira; ki itara Oluwa maba pa o run **<u>Esekieli 5: 11-13.</u>** Ti o koba feki idajo Oluwa farahan ninu aiye re, so iwa igboran po pelu itara re fun ise rere.

**<u>Olorun funrare ni itara fun wa</u>**

Lotito, Oluwa fe ki a ni itara fun ise ohun, sugbon Oluwa ni o koko ni itara fun awa eda-enia ti o da ni aworan ara Re. Eleda wa ni itara fun awon enia Re, O si tun ni itara lati mu awon ileri ti o se fun awon ti o gbagbo, ti won si duro de e, se lai-jafara.
Ao soro lati inu awon ese-bibeli ti won fihan gbangba, awon ohun ti Oluwa ti se ninu itara Re ati awon iyorisi awon igbese na.

**<u>Itara Olorun ni o mu Kristi wa sinu aiye:</u>** Itara ti Olorun Olodumare ni fun awa eda-enia ni o mu Jesu Kristi Oluwa wasi aiye. Olorun ni itara fun awa asayan ati pataki-julo ninu awon eda-owo Re ti o da sinu aiye, debipe " O fi omo bibi re kansoso funni, ki enikeni ti o ba gbagbo maba segbe, sugbon ki o le ni iye ainipekun" **<u>Johannu 3: 16</u>**. A ri aridaju wipe asotele inu iwe Isaiah wa si imuse nitori itara Oluwa. Bibeli wipe "a bi omo kan fun wa, a fi omokunrin kan fun wa: ijoba yio si wa ni ejika re: ao si ma pe oruko re ni Iyanu, Oludamoran, Olorun Alagbara, Baba Aiyeraye, Omo-Alade Alafia. Ijoba yio bi si i, alafia ki yio ni ipekun: lori ite Dafidi ati lori ijoba re, lati ma to o, ati lati fi idi re mule nipa idajo ati ododo lati isisiyi lo, ani titi lai. **<u>Itara Oluwa awon omo-ogun yio se eyi</u>**" **<u>Isaiah 9: 6-7.</u>** Yala o gbagbo tabi o ko gbagbo, itara Olorun Olodumare ni o mu Jesu Kristi Olugbala wa wasi inu aiye lati wa r'awa-pada kuro ninu ese wa. <u>A fun wa ni anfani ni igba keji nipa ironupiwada, lati tun awon ona wa se, ki a le ba Eleda wa l'aja.</u>

**<u>Itara Olorun gba Israeli sile lowo Sennakerubu:</u>** Itara Olorun ni o gba awon omo Israeli sile lowo Sennakerubu oba Assria, ni igbati o gbogun ti Jerusalemu. Sennakerubu pelu awon emewa re, ta abuku ba Oluwa; besini won so oro-odi si Eni-mimo Israeli ti won si p'egan Olorun alaaye. Oba Hesekiah ranse si woli Isaiah lati beere lowo Oluwa nipa isele yi. Itara Oluwa dabobo ilu Jerusalemu, besini angeli Oluwa pa awon oga-ogun ati awon asiwaju-ogun Sennakerubu. O pada pelu itiju si ile re, nibiti on pelu ti ku iku eleya **<u>Isaiah 37: 21-32, 2 Awon</u>**

**oba 19: 20-31.** Isoro k'isoro ti o le ma dojuko o lowolowo, tabi wahala ti o mu okun-emi re dani yio di itan; bi o ba le ni itara fun ise Oluwa. Olorun Olodumare ti o gba awon omo Israeli sile, yio san esan ise rere re,nipa gbigba o sile lowo ogun ti nja o; nitori itara Re fun o.

## Mura lati jiya nitori itara re

Boya o gbagbo tabi o ko tile gbagbo, o ba o lara mu tabi o ko fe, o ni lati jiya ni ona kan tabi omiran; ninu igbesi aiye re, nitori itara re. Ti ijiya yi ba w'aye, o je ohun ti o wa ni ibamu pelu Eko Bibeli.

**Kristi fi apere yi le'le:** Jesu Kristi jiya pupo nitori wa, ti o si pari irinajo na si iku ori-igi agbelebu. O fi apere yi l'ele fun wa, O si nfe ki a tele awon isise On. A ni lati ranti wipe "inu eyi ni a pe wa si: nitori Kristi pelu jiya fun wa, O fi apere sile fun wa, ki awa ki o le ma to ipase Re **1 Peteru 2: 21**. Ti Jesu Kristi ba le jiya fun itara ti o ni fun ise Baba Re, eyi tumo si wipe kosi eniti koni jiya nitori itara ti o ni fun ise Oluwa.

**O ni lati gbagbo ki o si jiya fun Kristi:** Ko-to fun enia lati wipe mo gbagbo ninu Jesu Kristi nikan, bikose ki enia jiya nitori itara ti o ni fun ise Oluwa, nigbana ni enia yio gbe igbe aiye imuse-ogo. Olorun sa ti fi anu yonda fun wa, kise lati gba Kristi gbo nikan, sugbon lati jiya nitori Re pelu **Filippi 1: 29**. Nitorina, e mase gbagbo tabi gbekele **nikan**, sugbon e mura lati jiya nitori itara ti e ni fun ise Re.

**Inunibini nduro de awon enia oniwa-bi-Olorun:** Gbogbo awon ti o fe ma gbe igbe iwa-bi-Olorun ninu Kristi Jesu, yio farada inunibini. Niwon igbati kosi ona abuja ni orun-ope, bi o ba ti ni itara fun ise Oluwa, Satani yio gbe awon enia buburu dide lati se inunibini si o; nitori igbagbo ati itara re **2 Timoteu 3: 12**. Mase jeki okan re daru tabi rewesi ni igbakugba ti o ba njiya nitori itara re fun ise Oluwa, sugbon bu s'ayo gegebi Peteru ati Johannu ti se nigbati won jiya; nitoripe won mu okunrin aro kan larada ni enu-ona Tempili ti a npe ni Daradara.

**Alabukun fun ni awon ti o ba jiya fun Kristi:** Enikeni ti o ba jiya nitori ododo tabi itara won fun ise Oluwa, alabukun fun ni won. Nitorina, e mase beru awon onise-ese tabi kominu nitori awon asoro-odi-si-Kristi **1 Peteru 3: 14**.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Kejilelogbon: Osu Kejo Ojo Keje, 2016**

**Akori Oro: Ni itara fun ise Oluwa – Apa keta**

**Eko Kika: Galatia 4: 11-18**

## Majemu Fun Awon Onitara Enia

Olorun yio fi idi majemu Re mule ninu aiye gbogbo okan ti o ni itara fun ise Re. Niwon igbati o je Olorun ti ko pa ipo-da, Olorun yio se bi O ti ma nse nipa gbigbe majemu Re kale ninu aiye re bi o ba ni itara fun ise Re:

**Finehasi:** Olorun fi majemu alafia fun alufa Finehasi omo Eleasari, majemu ise-alufa yio si je tire ati ti iru-omo re lehin re titi-aiye; nitoriti o ni itara fun Olorun re, o si setutu fun awon omo Israeli **Numeri 25: 12-13**.
Olorun ti o fi idi majemu alafia ati ise-alufa aiyeraye mule ninu aiye Finehasi nbe laaye, yio fi idi majemu Re mule titi-lai ninu aiye re, bi o ba ni itara fun ise Re.

**Dafidi:** Dafidi ni itara fun ise Oluwa, o si ro lati ko ile fun Oluwa. Lotito Oluwa ran Natani si wipe kise on ni yio ko ile bikose omo re ni yio ko ile fun Oluwa. Amo Olorun fi idi majemu Re mule ninu aiye re nigbati o wipe "Nigbati ojo re ba pe, ti iwo o sun pelu awon baba re, emi o gbe iru-omo re leke lehin re, eyiti yio ti inu re jade wa, emi o si fi idi ijoba re kale. On o si ko ile fun oruko mi, emi o si fi idi ite ijoba re kale lailai. Emi o si se baba fun u, on o si je omo mi.
Bi o ba dese, emi o fi opa enia na a, ati ina awon omo enia. Sugbon anu mi ki yio yipada kuro lodo re, gegebi emi ti mu u kuro lodo Saulu, ti emi ti mu kuro niwaju re, ao si fi idile re ati ijoba re mule niwaju re titi lai: ao si fi idi ite re mule titi lai." **2 Samueli 7: 12-16**.
Olorun mo awon ise okunkun, tori re ni O se fi **edidi** di majemu na, ki o ma sese fun enikeni lati baaje ati ki Esu maba yi danu.
Oluwa so ninu iwe Jeremiah wipe "Bi enyin ba le ba majemu mi ti osan je, ati majemu mi ti oru, ti osan ati oru ko le si li akoko won; Nigbana ni majemu mi pelu Dafidi, iranse mi le baje, pe ki on ki o ma le ni omo lati joko lori ite re; ati pelu awon omo Lefi, awon alufa, awon iranse mi. Gege bi a ko ti le ka iye ogun-orun, tabi ki a le ka awon iyanrin eti okun: beni emi o so iru-omo Dafidi iranse mi di pupo, ati awon omo Lefi, ti nse ise iranse fun mi." **Jeremiah 33: 20-22**.
Niwon igbati a ti mo asiri aseyori oba Dafidi, ni itara fun ise Oluwa, Ki o le fi

idi majemu Re mule ninu aiye re. Yio si fi **edidi** di majemu na, ki o ma ba sese fun Satani lati baaje.
Majemu yi ni a muse, ti a si fi idi re mule nigbati Jesu Kristi oba titi-lai ti o njoba titi-aiye wa lati iran Dafidi. E jeki a ma ranti wipe Jesu Kristi fi ara Re se irubo, ki on ki o le ra wa pada kuro ninu ese gbogbo, ki o si le we awa enia kan mo fun ara re, fun ini on tikalare, awon onitara fun ise rere. **Titu 2: 14.**
Ti o ba fe wa lara awon asayan-enia tabi enia-oto Kristi, ni itara fun ise Baba re ti nbe ni orun. Ti o ko ba feki iku-oro Jesu Kristi ori igi agbelebu je lasan, ni itara fun awon ise rere.

## Lo Itara Re Ni Ona Ti O Pe'ye

Itara je okan lara awon iwa rere ti eda-enia le ni, sugbon e mase ni itara fun awon ohun ti ko le'to, e ma lo itara yin ni igbagbogbo fun ise Oluwa ati awon ohun rere.

Opo enia ninu aiye loni ni won ni itara, sugbon ti won ndari re si afe-aiye ati awon ohun asan aiye yi. Awon wonyi nru okan opolopo enia soke lati ma se awon ohun ti ko le'to, ti ko si le muni jogun ijoba Olorun.

**Jeki itara re ru awon enia soke fun rere:** Ara mi, e jeki itara yin mu awon enia se ife Olorun, besini ki o ru okan awon enia soke lati se ohun ti o ye, ti o si se itewogba niwaju Oluwa **2 Korinti 9: 2.**
Itara re ko gbodo ru awon enia soke lati se ise-ibi, sugbon o gbodo jeki won fi ara won fun ise Oluwa ki won si ma wa idagbasoke ise na ni gbogbo igba.

**Ni itara fun awon ebun Emi:** Enia ti ko ni ebun-emi dabi eniti o ti ku sugbon ti a koti gbe sinu koto. Satani ati ite-okunkun yio ma lo agbara lori onitohun tabi ki won ma yan a je, nitori iru eni-be koni ipa tabi ona-emi lati ba Olorun so oro.

Emi ni Olorun, O si le ba enia so oro tabi fi ara han nipa emi nikan. Nigbati o ko ba ni ebun-emi bawo ni Oluwa yio se to o si ona lati dari irinajo re tabi abo pipe lori re? Lati isinyi lo, e jeki a ni itara fun awon ebun-emi ti ao lo lati fi idi ijo-Olorun mule, ti ao si fi wa idagbasoke re ni gbogbo ona; lati so di iyin-logo ni ibi-gbogbo labe orun yi **1 Korinti 14: 12**.
Ti o ko ba ni awon ebun-ofe ti Oluwa nfi funni, wa kun itara re ki o le ni. Ti o ba ti ni awon ebun-emi yi, sa ipa re ki a le fikun awon ti o ni ati ki o le ma dagba si ninu emi. Mase si awon ebun wonyi lo, sugbon lo won fun idagbasoke ati

ifesemule ijo Oluwa.

**<u>Ni Itara Fun Awon Eni Ami-ororo Ati Enia Olorun</u>**

A ni lati ni itara fun ilera awon eni ami-ororo Oluwa. Awon eni ami-ororo wonyi le je awon oluso-aguntan/alufa/Oluko/alagba ninu ijo wa. A ni lati fi owo sowopo pelu won ki won le se aseyori ati aseyege ninu ise won.

**<u>Awon ara Korinti ni itara fun Paulu:</u>** Titu mu irohin ayo wa lati odo awon ara Korinti, eyiti o tu Paulu ninu ti o si mu iwuri ba. Lakoko, awon ara Korinti banuje won si kabamo nitori awon asise won, sugbon nwon nse aferi Paulu; won si ni itara fun ilera re **<u>2 Korinti 7: 7</u>**.
Ara, e jeki a ni itara fun ilera awon asiwaju wa, ki a ti won lehin, besini ki a fi ifimo-sokan ba won sise po; ki won le se aseyori ninu ipe won, ni ona ti yio fi je ere fun gbogbo Kristiani.

**<u>Jeki itara re fun awon eni ami-ororo ni eri:</u>** Paulu aposteli jeri wipe Epafra nfi iwaya-ija gbadura fun awon enia Oluwa ni nbe ni Laodikea ati Hierapoli ki won le duro ni pipe ati ni kikun ninu gbogbo ife Olorun. Nitori idi eyi, Paulu fi owo so'ya wipe o ni itara nla fun awon enia na **<u>Kolosse 4: 12-13</u>**.
Bawo ni iwo na ti le fihan wipe o ni itara fun awon eni ami-ororo ati enia Oluwa? E jeki itara yin di mimo ki awon enia le gba eri yin je wipe, e ni itara fun awon enia Oluwa.

**<u>Josua jowu fun Mose:</u>** Olorun pase fun Mose ki o yan adorin okunrin ninu awon agba Israeli lati kun lowo sise. Awon wonyi duro yi ago-ifarahan Oluwa ka, sugbon awon okunrin meji ninu awon ti a yan Eldadi ati Medadi ko ba won pejo, won wa ninu ago won.
Nigbati akoko to, Oluwa mu lara emi ti nbe lara Mose, o pin si ara awon agba na, gbogbo won si beresini sotele, pelu awon meji ti nbe ninu ago tiwon. Josua iranse Mose si wi fun Mose ki o da awon ti nsotele ninu ago ara won lekun. Mose si wi fun u pe, "iwo njowu nitori mi? gbogbo enia Oluwa iba le je woli, ki Oluwa ki o fi emi Re si won lara" **<u>Numeri 11: 16, 24-29</u>**.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Ketalelogbon: Osu Kejo Ojo Kerinla, 2016**

**Akori Oro: Ni itara fun ise Oluwa** – Apa kerin

**Eko kika: Galatia 4: 11-18**

## Apejuwe awon enia ti won ni itara

Opolopo awon onitara enia ni a menuba ninu bibeli, awon ti itara won ni ipa rere ninu aiye awa eda-enia ni igba aiye won ati lehin iku won.

Bibeli soro nipa itara awon enia wonyi:

- **Gideoni** ti Oluwa lo lati gba awon omo Israeli sile lowo awon ara Midiani **Awon onidajo 6: 11-16**
- **Baraki** ti o ko ipa pataki lati segun Jabini oba awon ara Kenaani ati Sisera olori ogun re **Awon onidajo 4: 1-8**
- **Samsoni** ti Oluwa lo lati te ori awon omo Filistini ba **Awon onidajo 15: 9-20**
- **Jefta** ti Oluwa fi Sihoni oba awon Ammoni ati awon enia re le lowo **Awon onidajo 11: 5-10**
- **Oba Dafidi** ti o bori Goliati alagbara awon ara Filistini, eyiti o fa isubu gbogbo awon omo Filistini patapata **1 Samueli 17: 41-51**
- **Samueli** ti o gbadura fun awon omo Israeli, ti Oluwa si san ara nla lati pa awon Filistini niwaju awon omo Israeli **1 Samueli 7: 2-14**

Gbogbo awon enia wonyi ni won fi itara fun ise Oluwa kun igbagbo won. A ni lati fi won se awokose, ki a si se afarawe won ki itan igbesi-aiye wa ba le ni itumo; ki awon enia si le ri ohun rere so nipa irirnajo-aiye wa **Heberu 11: 32-34**.

**Itara Finehasi**: Nigbati Israeli joko ni Sittimu, awon enia na si beresi ise pansaga pelu awon omobinrin Moabu. Nwon si pe awon enia na si ebo orisa won; awon enia na si je, nwon si teriba fun orisa won. Israeli si da ara re po mo Baali-peoru: ibinu Oluwa si ru si Israeli.
Okan ninu awon omo Israeli wa, o si mu obinrin Midiani kan to awon arakunrin re wa ni oju Mose ati gbogbo ijo awon omo Israeli, ti nsokun ni enu-ona ago ajo. Finehasi si dide larin ijo, o mu oko kan li owo re; o si to okunrin Israeli na lo ninu ago, o si fi gun awon mejeji li agunyo. Arun si da larin awon

omo Israeli. Awon ti o si ku ninu arun na je egba mejila.
Oluwa si so fun Mose pe, Finehasi ti yi ibinu mi pada kuro lara awon omo Israeli, nipa itara re nitori mi larin won, ki emi ki o mase run awon omo Israeli ninu owu mi. **Numeri 25: 1-11**.
Fi itara re jirebe, ki o si fi yi ibinu Olorun kuro lori awujo tabi orile-ede yin. Ranti, mase si itara re lo, sugbon lo fun igbala emi awon enia ati lati da emi awon enia si, bi ti Finehasi.

**Itara Elijah**: Elijah ni itara fun ise Oluwa ni igba aiye re gegebi awon ese bibeli ti wi. Ni igbati awon omo Israeli ko majemu Oluwa sile, ti won wo pepe Oluwa lule, ti nwon si fi ida pa awon woli re titi ti o fi ku Elijah nikan; ti won si nwa ona lati gba emi Elijah pelu. Ninu gbogbo hila-hilo yi Elijah duro sinsin pelu igbagbo, o si nfi itara se ise oluwa **1 Awon oba 19: 9-14**.
Ti iwo na ba ni itara fun ise Oluwa, ni igbati awon enia ba npadanu emi won, Olorun yio jade si o; yio si fi abo re ti o nipon bo o, yio da emi re si, besini aburu ki yio wa sori re tabi sunmo ago re.

**Itara Paulu**: Paulu ni itara ni ona ti ko ye, ki Kristi to ba pade, lotito; eleyi ta opolopo awon ojugba re yo ninu isin awon Ju larin awon ara ilu re; o si ni itara lopolopo si ofin atowodowo awon baba won **Galatia 1: 14**.
Ti o ba dabi Paulu, ti o si ti lo itara re ni ona ai-to, ni ibere pepe aiye re. O to ge, yipada, ki o si bere sini lo itara re ni ona ti o se itewogba si Olorun; sugbon ti ki si se lati te asa tabi ofin atowodowo awon baba yin lorun.

Ti o ba je enia ti o fi tokantokan gba esin, ti o si nse ohun gbogbo lati muki o nira fun ijo-Oluwa lati fi idi mule. Bi o ba wa lara awon enia ti ko fe ki ijo-Olorun gberi, debipe awon enia nwipe o ni itara, nipa sise inunibini si ijo; ti o si je alailegan nipa ododo ti o wa ninu ofin bi Paulu **Filippi 3: 6.**
Tun ero re pa, ki o si kuro ninu sise inunibini si ijo Oluwa, eyiti Kristi fi eje re ra pada. Lati isinyi lo, wa otito ri, fi ara mo otito, ki o si fi itara sise fun idagbasoke ijo Olorun alaaye.

Oye oro-Olorun ye Paulu ki o to pe ju, o si dari itara re si sise ise Olorun, gegebi gbogbo awa olufokansin **Ise awon aposteli 22: 3**.
Loni, eyi je ohun isiti fun gbogbo awa Kristiani, torina, e jeki a ni itara fun ise Oluwa ki o to pe ju. Akoko ti a ti si itara wa lo tito, e jeki itara wa fun ise Oluwa mu erin ati ayo ba awon enia Olorun.

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**__Itara ti Jehu:__** Asotele ti Oluwa ran si idile Ahabu nipase Elijah wa si imuse nipa itara Jehu. Olorun lo itara Jehu lati gbesan eje Naboti ara Jesreeli ti a pa nitori ati gba ogba-ajara re. **__1 Awon oba 21: 17-25, 2 Awon oba 10: 7-10, 15-16__**.

Lakotan, ni igba ewu ati igbakugba ti o ba wa ninu isoro, gbadura si Olorun wipe ki o boju-wole lati ibugbe iwa mimo ati ite-ogo re; ki o si fi agbara-itara re gba o. So fun Oluwa ki o fi eyonu han si idile re, ki o si sanu fun o. **__Isaiah 63: 15__**. Gba adura si Olorun ki o fi oro re se pataki ni ookan aiya re, ki o si so gbogbo wahala aiye re di itan nitori itara ti o ni fun ise re.

**__Edidi: Ifihan 3: 15-19__**: "Olorun mo ise re, pe iwo ko gbona beni iwo ko tutu: On iba fe pe ki iwo kuku tutu, tabi ki iwo kuku gbona. Nje nitoriti iwo se ilowowo, ti o ko si gbona, beni o ko tutu, On o po o jade kuro ni enu re. Iwo nwipe ' emi li oro, emi npo si li oro, emi ko si se alaini ohunkohun'; ti iwo ko si mo pe, osi ni iwo, ati are, ati talaka, ati afoju, ati eni-ihoho: On fun o ni imoran pe ki o ra wura lowo on ti a ti da ninu ina, ki iwo ki o le di oloro; ati aso funfun, ki o le fi wo ara re, ati ki itiju ihoho re ki o ma ba han, ki o si fi ogun kun oju re, ki iwo ki o le riran. Gbogbo awon ti on ba fe ni o nbawi, ti o si nna: nitorina, **__ni itara fun ise Oluwa ki o si ronupiwada awon ese re"__**.